# IROHIN IMỌLẸ

*IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA*

No. 1,421 THURSDAY AUGUST 5, 1965 (2D)


10 AUG 1965

## Ọlọpa Kan Ji Basikulu Gbe

**IKẸJA:—Ninu ọsẹ to kọja lọ yi ni ọkunrin Ọlọpa Ijọba ibilẹ ti Mushin Isaac Shogunam fi ara han ni iwaju ile ẹjọ kekere ti ilu Ikẹja pe ọdaran na ji kẹkẹ mẹta gbe ninu ọdun to kọja lọ ni ọgba awọn Ọlọpa ti Ijọba ibilẹ Mushin.**

Ninu ẹjọ ti Agbejọro fun Ọgbẹni Simeon Ajueyẹ ati Ẹlẹri ti iṣe Ọlọpa Ibilẹ na Ọgbẹni Elijah kẹkẹ ṣe alaye fun ile ẹjọ na pe on fi kẹkẹ on si ọdọ ọrẹ on ni ọgba awọn Ọlọpa Ijọba ibilẹ ti ilu Mushin nigbati on lọ fun irin ajo kan o tun ṣe alaye pe nigbat on de lati irin ajo ti on lo ni on gbọ pe kẹkẹ on ti sọnu.

Ninu ọrọ ọkan ninu Ọlọpa Ijọba ibilẹ ti ilu Mushin Ọgbẹni Sule fun ile ẹjọ ni o ti ṣe alaye pe Ọlọpa ọdaran na feran lati ma ra awọn kẹkẹ ti Ijọba ibilẹ ti ilu Mushin ba ta ni gbanjo, O ni ọdaran na ta kẹkẹ mẹta fun Ọgbẹni Sule ti nṣe iṣe kapinta.

Ninu awọn kẹkẹ mẹta to sọnu ni awọn Ọlọpa ri meji ko wa si ile ẹjọ la ti fi han Adajọ ile ẹjọ na Adajọ ti sun gbigbọ ẹjọ na si ọrọwaju.

# IJỌBA IWỌ ORUN FẸ RỌ AKARIGBO KURO L'OYE?

SHAGAMU:— Agba iyanu nla ni irohin ti o kan gbogbo enia ku ni kutukutu owurọ ana je nigbati nwọn gbọ wipe, ija ti o wa larin awọn afọbajẹ ati awọn ọmọ ẹgbẹ Osugbo ni Ijẹbu Rẹmọ wipe awọn fẹ le Alaiyelu a Moses Showẹmimọ Awolesi, Akarigbo Ọba Ijẹbu-Rẹmọ kuro lori Oye ni ana ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ti tun bẹrẹ.

Ninu ipade kan ti awọn enia na ṣe ninu gbọngan Shagamu ni irọlẹ ijẹta ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi awọn enia a sọ wipe awọn fẹ le Ọba na kuro lori oye gẹgẹbi Ọba.

Ninu awọn ẹsun ti awọn enia na ka si Ọba Akarigbo lẹsẹ, ni wipe Ọba Alaiyeluwa ko tẹle gbogbo ileri ati ipinnu rẹ ti o ṣe ati gbogbo ohun ti o s wipe on yio ma a ṣe fun awọn ara ilu ati awọn afọbaje.

Awọn enia na sọ wipe, ninu oṣu kẹta ọdun yi ni awọn Ọba alaiye ni Ipinlẹ Iwọ Orun a i edeaiyede ti o wa larin awọn ati Ọba na, ti Ọba na si jẹwọ pẹlu ileri gbogbo ohunti awọn enia na ba fẹ ni oa yio ma a ṣe fun wọn.

Ni u awọn ohunti awọn enia n sọ wipe Ọba a gba lati ṣe ni, wipe Ọba na gbọdọ da ile kan eyiti o wa ni kawọ rẹ silẹ, o gbọ d san ẹgbẹta ponun (£600) owo kan ti o wa ni owọ rẹ.

Agbọrọsọ awọn Afọbaj ni Shagamu tun fi ye o iwe Irohin wa wi pe Ọba na t n gbọdọ maa lu ilu gbadu ti o wa ninu Aafi r gẹgẹ bi aw n ọba ti o jẹ siwaju r mi nṣe

Ni ipari ijok wọn ọjọ na, lẹhinti awọn enia na ti ka ẹsun wọn yi si Ọba na lẹsẹ tan Ọba na gba wipe gbogbo awọn ohu ti won wi a ni on yio ma ṣe.

Ṣugbọn Agbọrọsọ awọn Ọba na so wipe Ọba Moses Awolesi ko ti san ẹgbẹta p nu (£600) owo ti igbimọ ijoko awọn Ọba so w-pe ki o san.

Bakanna ẹwẹ ni ilẹ kan t o wa ni ika ọ Ọbọ na ti nwọn so wi-pe ki o fi silẹ, fun awọn afobajẹ ki ija na le ba pari Ọba na ko fi silẹ titi di igba ti on fi nsọrọ yi.

Ni ipari, Agbọrọsọ awọn afọbajẹ na tun sọ wipe ilu ti gbogbo awọn sọ wipe ki Ọba na maa lu gẹgẹbi iṣe awọn enia yoku ti nwọn ti jẹ Ọba siwaju Ọba na Ọba Awolesi ko lati lu ilu a ko si lu ilu na titi di igbati on fi nsoro yi

Lẹhin gbogbo awọn ẹsun wọnyi ni gbogbo awọn enia mẹtalelọ-gbọn ti nwọn wa ninu ipade wa na ṣe ip n nu wipe awọn yio le Ọba Moses Showẹmimọ kuro lori oye patapata ni ọtẹyi ni ko si tun le pari ọrọ na mọ.

Awọn afọbajẹ na wa fi ohunsọkan ninu ipinnu wọn ọjọ na wipe awọn yio kọwe si gbogbo awọn Ọba alaiye ti nwọn ba aw n pari ija na tẹlẹ wipe rogbodiyan a ti tun bẹrẹ o.

Lẹhinna ni nwọn wa kọwe si Alake Aba okuta, Ọlọwọ ti Ọwọ ati Alhaji Saka Layọna, Minista Alamojuto eto awọn Ọba ati Ijoye fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Ninu iwe ti awọn enia na kọ ni nwọn ti sọ ipinnu wọn wipe, "Lẹhinti Ọba Awolesi ti kuna lati mu ileri rẹ ṣẹ, ti ko si tun tẹle imọran awọn Ọba Alaiye, awọn fun Ọba na ni ogoji ọjọ (40 days) lati fi palẹ ẹru rẹ mọ, ki o si jade kuro ninu Aafin rẹ ki ọjọ na to pe."

Aw n enia na ti kọwe ranṣẹ lati fi ipinnu wọn han Ij ba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria wipe awọn fẹ rọ Ọba Awolesi loyẹ, ọrọ na ko si gbọdọ ju ogoji ọjọ lọ ki Ọba na to jade ninu Aafin rẹ fun awọn.

Agbọrọsọ awọn Afọbajẹ na tun s ọ wipe o ti le ni ọsẹ kan nisisiyi ti aw n ti nṣe ipade lori ọrọ Ọba na ki awọn to wa fi ori ọrọ a ti si wipe yiyọ ni awọn yio yọ Ọba Ọba na kuro lori oye.

Lẹhin eyi i onirohin wa ni Shagamu wa l ọ si A fin Ọba na lati lọ fi ọro w ọrọ wo lẹnu rẹ ṣugbọn nwọn sọ wipe Ọba na sun lọ—wọ o si di irọle ki o fo ji.

Ṣubgọn okan ninu awon enia ti o wa ninu Aafia Ọba wa sọ f u n onirohin wa w i p e awon ko ti ri iwe kankan gba lati odo awon Afobajẹ w pe ki Akarigbo kuro lori oye rẹ, Nwon ni awon ti ngbo oro na gẹgẹbi agboso lẹnu awon ara ilu ati ninu awon Iwe Irohin

Ṣugbon Agbẹroso Ọba na so f u n oniwe Irohin wa wipe Ọ b a Awolesi ti san ẹgbẹta ponun (£600) ti nwon so wipe ki o wa s a n Bẹẹni o si t fi lẹ ti awon afobajẹ fẹ g b a kuro lowo rẹ silẹ fun won lati igbati nwon ti pari oro na larin a r a won ati gẹgẹbi Igbimo ijoko awon Ọba ti ṣ e pa a laṣẹ ni o j o ti nwon pari ija na.

Ọkan ninu awọn afọbajẹ na sọ pe, gbogbo wahala ti a nṣe lati pari ija na, ofo lo jasi.

"Ko wa si ohun miran fun wa mọ ti a le ṣe ju pe, ki a rọ Ọba na loye lọ"

Laipẹ yi ni a o yan Ọba titun miran ti a fẹ

Wo Oju Ewe Kẹfa



**Oba Moses Awolesi**
Akarigbo Ijẹbu Rẹmọ

# OLUWA YIO BERE LỌWỌ RẸ (Apa Kini)

Mo ki gbogbo enyin o igbagbọ jakejado ni orilẹ aiye ẹ ku isẹ Oluwa, mo si tun ki ẹnyin ol ri ile, Alufa, Bisọbu, Evangelist Woli a i bẹbẹ lọ, Oluwa ko ni se nyin ni ẹni igbagbe ni ọjọ ikẹhin, Amin.

## Lati Owo Pastor Olu, Mushin

Ọrọ mi ti oni yio duro lori Oluwa yio bere lọwọ Rẹ mo lero wipe, ẹ ko gba gbe ọrọ ti mo sọ ninu Irohin Imọlẹ nipa okunrin kan ti o nlọ si ajo ti o pe awọn ọmọ-ọdọ rẹ jọ ti o ti pin talenti fun wọn gẹgẹbi agbara olukuluku se to.

O fun eyi agba ni marun ekeji o si fun ni mẹji ati ẹkẹta ni ẹyọ kan lẹhin eyi o ni mu ọna ajo rẹ pọn Lẹhin ọjọ diẹ sẹhin emi o pada de lati wa wo isẹ ti awọn ọmọ-ọdọ na se pẹlu talẹnti wọn.

Nigbati o de t o si bere lọwọ ekini ti o gba marun o si wipe Oluwa iwọ fi talẹnti marun fun mi si wo mo jere talẹnti marun miran. Oluwa rẹ wi fun pe, o seun iwọ ọmọ ọdọ rere ati olọtọ iwọ se Olotu ninu ohun diẹ emi o mu Olori ohun pupọ, iwọ bọ sinu ayọ Oluwa rẹ.

Eyiti o gba meji si jere meji miran o si tun sọ fun baranna gẹgẹbi ti asiwaju.

Sugbọn eyiti o gba ẹjọ kan ti o lọ ri tirẹ mọ inu ile ti o si aso isọkusọ ni a gbe sinu okunkun biri biri nibiti ẹkun on ipahinkeke yio gbe wa Lẹhin eyi o tun gba talenti ọwọ rẹ fun ẹniti o ni mẹwa

Nitori ẹnikẹni ti o ba ni ti a o fi fun yio si ni lọpọ lọpọ sugbọn li owọ ẹniti ko ni ni a o tilẹ ti gba eyiti o ni

Fun alaye kikun nipa Itan yi mo pe akiyesi nyin si inu Iwe Mimo ti Ọlọrun ti ise Matteu 25:14 30

Ọrọ mi si enyin enia Ọlọrun nipa itan yi ni wipe ẹ lọ ronupiwada ki ẹ si di atunbi. Nitoripe mo fi oju inu wo inu aiye wa ode oni boya ni a fi lori ẹniti a o gba la ni ọjọ Ikẹhin

Ọna ti awa enia ode oni ngbe esin Ọlọrun gba ti yato si Ilana Ọlọrun patapata Olukuluku kan usẹ eyiti o wu wọn, wọn si lero wipe awọn nsin Ọlọrun loju ara wọn, a fi awọn enia diẹ nikan

Sugbọn ẹyin ti ẹ pe ara nyin ni ojisẹ Ọlọrun na ọpọ ọpọ ti ya kuro ni Ilana Ọlọrun. Ti ẹlomiran ba ma se Iwasu ninu Sọọsi iwasu bi wọn yio ti se da owo nikan ni yio mase fun awọn enia

Nipa bayi ẹniti ko ba ni owo yio bere si ronu, sugbọn ẹniti o ni owo, ti a ba ni ki won da sile marun (5s) wọn yio da sile mewa (10) Nib ti enikan ko ri silẹ kan 1s da.

Ese ti ẹniti o ni owo ko sẹ ran alaini lọwọ? Awọn Alufa miran si tun wa won yio ma na owo ile Ọlọrun si apo ara nwọn, Ti nwọn ba ni bi egbẹrun pọnun si Bank (£1000) nwọn ko ni mọ bi owo na ti se rin kuro ni Bank. Njẹ iru eleyi ni Jesu se nigba aiye rẹ?

Awon elomiran si tun pe ara wọn ni aladura, nwọn yio ma a pa irọ tan eniyan jẹ kakiri. Aiye yio parẹ loni nkan yio se ni ọla nwọn ti gbagbe ọrọ ti Jesu sọ ninu iwe Mark 13 ẹsẹ 32 pe sugbẹn niti ọjọ mọ o kosi ki tilẹ ise awọn Angẹli ọrun, tabi ọmọ, bikose Baba mi nikansoso.

Mo si tun pe akiyesi ẹyin enia si ọrọ Jesu ni o sọ ba yi pe Nitorina bi ẹnikan ba wi fun nyin pe, Wo Kristi mbẹ nihin yi, tabi wo O mbẹ ọhun, ẹ mase gba a gbọ.

Nitori awọn eke Kristi ati awọn Woli yio dide nwọn o si fi ohun iyanu han tobẹ bi o se ise, nwọn ba tan awọn ayanfẹ papa Marku 13: 21-22.

Sugbọn araiye feran okunkun ju imọlẹ lọ. Aiye si kọ otitọ sugbọn mo fẹ ki ẹ ran ti pe, enyin yio mọ otitọ, otitọ yio si sọ nyin di ominira

Awon ẹlomiran ẹ ọga ni ibi isẹ. ti nwọn ba fẹ gba enia si ibi isẹ kan nwọn yio tun fẹ ki oluwarẹ fun won ni owo ki nwọn to le gba nwọn. Sugbọn ẹ jọwọ mo fi iyọnu ọlọrun bẹ nyin ẹ lọ ronu piwada ki ẹ si mọ pe nipa agbara Ọlọrun ni ẹ fi wa ni ipo yi.

Ore ti ẹ ba nse fun enia, ẹ mase duro de ere rẹ, ni ọdọ enia kan talẹnti nyin ni ẹ lo yẹn. Ẹsan ti Ọlọrun o ja gbogbo rẹ lọ, se ẹ gbọ Ore-Ọfẹ ti Ọlọrun ni se pataki julọ o.

Ni aiye wa ode oni, mo fẹ ki o ye gbogbo ẹnyin enia wipe, Ọlọrun ti binu si araiye gidigidi papa ni orilẹ ede wa yi.

Ipọnju pọ, rogbodiyan si pọ pẹlu ni orilẹ-ede aiye. Sibẹsibẹ a ko ronupiwada kuro ninu ẹsẹ? Owe awọn baba wa kan ni o sọ bayi wipe; "Kaka ki o san lara ajẹ, o nfi ọmọ rẹ bi obinrin eiyẹ mbi lu eiyẹ.

Ẹlomiran tilẹ ti sọ ile aiye wa yi di ti Osẹlu awọn a ni Oloye Aw lọwọ ni ko jẹki a ri owo na ati wipe o tilẹ ti, ti ilẹkun owo ti o ba ti jade a jẹ wipe owo jade ni yẹn. Ẹ jọwọ ẹ fi ohun ti Ise ti kesari fun kesari ki ẹ si fi ohun ti ise ti Ọlọrun fun Ọlọrun

Awọn kan si gbaduro la ti maa kọ ọrọ yi sinu iwe M gba Awolọwọ gbọ Ẹ fi ọpẹ fun Oloye Awolọwọ nitori ti o jẹun nitori ti anu rẹ duro laila! Njẹ eleyi ha dara bi? Ara eleyi ni fa ibinu Ọlọrun si Orilẹ aiye.

Ẹnyin ẹ to yo, awọn kan nlọ sinu osupa ati lọ dan ise Ọlọrun wo? Iru eleyi ha dara bi? Awọn kan je nwọn ma tan won jẹ ni ko si Ọlọrun rara? Nwọn ti

Wo Oju Ewe Karun

## Adewale Di Oloye



Aworan yi nigbati afọbajẹ fi njawe oye le Oloye Adewale (ẹniti gbogbo enia mọ ni ọmọ d da) ninu Iga Idunganran ni ọjọ kẹrinlelogun osu keje ọdun yi.

Awon ọrẹ ojulumọ ati mọlẹbi pọ lọ jara ninu Iga ọba Oyekan nigbati Oloye Adewale ti njẹ oye Asipa ilu Eko awọn ti o si lọ duro de ni idita inu ile rẹ to wa ni Eko ko niye lai ti sọ awọn to lọ duro de ninu ile rẹ miran ti o tun wa ni Yaba

Awọn ẹlẹsin i ẹsin dara ni ọjọ na ko si ere ti nwọn ko fi ẹsin se tan se ni awọn ẹsin na njo bi enia oye yio mọri, o asẹ

# A.B.D. Olowe

## Lati Ọwọ 'Kunle Adeniji Mushin

A A gbọn ta ba ni agbon o binu jo agbon silẹ
B. Baba njona ẹ mbere Irugron
D. Dada ko le ja ṣugbọn o ni abur to gboju
E. Elegede so loko asopa-nbina
Ẹ Fija re fun Ol r n ja fọwọ leran
G Gele o dun bi ka mo-we ka mọ we ko da bi ko yẹ ni
GB. Gbangba dẹkun kode-re wọ
I. Itakun to ni ki Erin ma gun Oke odo, on ati Erin lo nlọ
H Haramu ni ole jija ẹ ma se jale mọ
J Janduku ọmọ ajitafa, ojọ ti oruto ta mu gbogbo enia ni Oru ma nmu
K Kawa ewi to lẹhin ka f'ọmọ fun abuke lẹ gbẹ-hin silẹ
L Labalaba to ba digbolẹ gun aṣọ rẹ a fava
M Malu ti ko n' iru Olu-wa Ọra ni ole esinsin fun
N Nangudu ku tan ka ri eni jẹ on ṣugbọn Erin ku Nangudu fi jẹ Ẹfọn ku oko Nangudu kan na fi je p lu
O Ọjuba iru ko denu aṣẹ-hin deni ko wọpọ
Ọ Ọpọlọpọ enia ni ko mọ pe ọpọlọ ni ọpọlọ lori
P Purọ lo nniyi ẹtẹ lo mu wa
R Riro ni ti enia ṣiṣe ni ti Ọlọrun
Ṣ Ṣiṣe sise ni nlu omode Ep
T Tanimọwo afi Oluwa
U Ukunku de Gambari de awo ri awo
W Were dun wo lọja Asi-wia se mu ṣe erin rin ta ni je bi iru wọn lọmọ
Y Yọkọlu yọkọlu ko wa tan bi, Iyawo gbọkọ san-lẹ ọkọ yọke

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQURARI (Jan 20-Feb 18) Iwọ yio jẹ igbadun ara rẹ ni ọsẹ yi awọn ọrẹ yio se iranlọwọ pupọ fun Ọ.

PISCES (Feb 19-March 20) Nipa ranlọwọ ọrẹ ni iwọ yio se gbe eru tẹ dori Maṣe tẹru Iwọ yio bori.

ARIES (March 21 April 19) Bi o tile je pe ọsẹ yi, yio le fun o ko ko awọn ẹgbẹ ni yio gbe ọ bori isoro gbo gbo ọsẹ Maṣe jina si awọn ọrẹ ninu ọsẹ

TAURUS (April 20-May 20) Ori re yio je tire lọsẹ itẹlọrun yio si wa fun ọ ọpọ ninu awọn ta wọ pẹlu oro yio pari si rere.

GEMINI (May 21-June 21) Iwọ yio ṣe orire lariu ọṣe yi ir njo si mbẹ lọsẹ rẹ iwọ yio ni ọrẹ titun kan ti yio se ọmi anfani ole jẹ ọkunrin ati obinrin

CANCER June 22 July 22) Ọrọ kan yio ru ọ loju lọsẹ yi ṣugbọn awọn ọrẹ yio yọ ọ ninu ijọgbọn na isẹ r, yio dara pẹlu iwọ si tẹ siwaju ki o si gbiyanju

LEO (July 23-Aug 22) Ọsẹ yi yio daru fun ọ wọ o si ri iṣe pupọ se Iwọ o si gbalejo pupọ

VIRGO (Aug 23 - Sept 22) Iṣẹwẹsi ọkan yio wa fun ọ lọsẹ yi gbogbo nkan ti o nlepa ko ni ṣe dede, suru lọbọ.

LIBRA (Sept 23 - Oct 23) Ọjọ oni dara fun ọ pupọ bi'o ti lẹ je pe iwọ o lese yio maṣe ri ididuro diẹ fi ori ti

SCOPIO (Oct 24 – Nov 22) Ọsẹ yi dara fun ọ i o o si jẹgbadun ara rẹ. i ọ o si ri ale ti yio dun mọ ọ ninu

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Ko ni sidamu ta bi wahala fun ọ lọsẹ yi Ọrẹ rẹ ia yio gba ọ ti imẹran, ki o gba ti se gb n nitori imẹran na dara pupọ.

CAPRICON (Dec 22 - Jan 19) Arẹ ọkan yio ba ọ jẹ, ọsẹ yi Ṣugbọn arẹ na ko ni pe kuro, Nipa suru ati ifọkan balẹ ni i ọ yio fi bori iṣoro gbogbo

## "URODL YSAN DRAGES"

Fun itọju tabi fifọ Apo Ile Itọ (Kidney Blinder) fun ọkunriu tabi obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọo lẹnu oruukuu, Ibadi, Gige tabi riro eri itọ, tabi itọ jijo enia itọ rukuruku Pipọn aikoleri itọ to iakuregbe orunkun owo ẹsẹ Ejika wiwu tabi riro.



Ara sisan, titobi aiko le gbe ra kọnkọn tabi kiakia didaju arinrigbakugba ati ori ṣirisi awọn aisan tabi amodi ba wọnyi ni egbogi aiọbidan yi yio wo san lara rẹ ni kiakia ti alafia yio si de si ọ. Meji rẹ o si ni ilu Naijiria nitori a sọra ki awọn eleru tabi awọn oni robirọbi ma ti orisi omiran ti ko ni lari fun o, maṣe gba rara! Owo re je Ṣile mẹfa ab o/6d owo Ọkọ sile kan 1/6d.) ati abo.

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street Lagos
Pho na22872 Nigeria (Ọja Ita Faji)

ATI NI ṢOBU

IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKEBỌLA IBADAN

## EGBOGI JEDIJEDI



CYCLOVEN

Aworan ebẹ yi fi han gba ngba biti jẹdijẹdi to wa lara re ti nyọ ọlẹnu ọi-gbagbogbo lbẹ ni a npe ni omusu tabi iho idi enia ibiti nma ngba iṣe igbọnsẹ Arun Jẹdijẹdi jẹ itan ninu modi ti o tara, ni pataki fun okurin ti o si ṣoro o pupo lati ṣe iwosan fẹtan patapata

Ọpolọpọ egbogi li owa t'a nta kakiri ode isisiyi ti nwọn ma apolowo nwọn un iwosan r e ṣugbọn bo-sa ni a le ri mẹwa ninu awọn ogun to le ṣe iwo-an aru n na daradara.

Awọn elomiran lero alpe boya bi wọn gbe lo si ile iwo san lati lo ge eyiti o ba nyo jade ri omusu on nipa bẹ awọn yio bọ lọwọ rẹ patapata

Ṣugbọn awa koro bẹ rara lẹhin ọdun diẹ iyọ u rẹ yio si tun bẹrẹ bakanna Orisirisi Jẹdijẹdi ni o wa Ekini ti o bẹrẹ aiko maṣe lẹbọnsẹ deede tabi lojojumọ, gigun kẹkẹ ologere Basikulu pupọ ẹlomiran ewu eran Sisa oniruru ohun adidun pupọ, pupọju nigba kugba jẹdijẹdi orisirisi ni o wa eso ni tirẹ? Bi o nyo sode ninu omusu tabi ti o ma nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnṣe tabi ti nrin o ninu omusu rẹ ti o ba jẹ bẹ bere egbogi CYCOVEN ti awọn Oyinbo Jamani ṣeṣe wa idi re ki o si dan wo o ri daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata ti a ta nigboro Naijiria bere ni:-

WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palm Church Street Lagos
Phone; 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji

ADEDUN CHEMIST
14,. Wakeman Street, Yaba

## Iwe si Olotu Irohin Imọlẹ

### IROHIN IMỌLE D'ARABA

Pelu ayọ ati inu didun mo ki Olotu ati awọn alabaşişẹ pọ bẹẹrẹ mo tun ki awọn to sişe lori bi awọn yio ti şe le gbe irohin na jade ati ranpa julọ Oludasilẹ iwe Irohin Imọlẹ pe ki nwọn ku işẹ emi yio şe opọlọpọ ajọdun kẹjọ ti iwe Irohin Imọlẹ şe ninu osẹ to koja lọ yi.

Eleyi jẹ ohunti o ba mi ninu oju lati gbọ pe Irohin Imọlẹ şe ajodun kejọ ti o de ilẹ Najiria pe mo ba mọ iru ọrọ ti o yẹ ki n kọ ranşẹ si Olotu lati le te e jade ki gbogbo awọn enia ri ka fun işe nla ti iwe Irohin Imọlẹ ti şẹ fun ile Igbimọna lakotan.

Eleyi yio jẹ didun inu awa to nka Irohin Imọlẹ lojojumọ bi a ba le ma gbọ tẹlẹ pe asiko tayi ni iwe Irohin Imọle yio şẹ ajajọ ajọdun rẹ Olotu a o si ma reti ni ọjọ miran.

Emi ni
R. A. Bakare
OMUPO

### A Dupẹ Lọwọ SHOYINKA

Inu mi yio dun pupọ bi olotu ba le gba mi ni aye ranpe ninu iwe Irohin Imọlẹ alarinrin ti o ni o wa ni ogbon ati oye lati dupe lọwọ Ọgbeni J O Shoyinka fun awọn itan aladun ti o fi nda wa lara ya.

Mo dupẹ pupọ fun ọpọlọ ti Ọlọrun fi ta lọrẹ, Olu wa ko ni gba ọpọlọ na lọwọ re aşẹ Iwaju ni opa ebiti re yio ma re si amin, nitori pe mogbadun itan Tanimehinola lopolopo.

Inu wa yio dun bi o ba le fi itan aladun miran to wa lenu wo eyiti yio dun ju Tanimehinola lọ

Ao ma reti awọn itan ala dun miran lati ọwọ Ọgbeni J O Shonyinka

Olotu mo dupẹ Ọlọrun yio ma ran Ọ lọwọ

Emi ni
Sẹrifatu Abatti
Eko.

### Iwa Yi Ko Dara

Inu mi yio dun bi Olotu ba le gba mi laye diẹ ni nu iwe Irohin Imọlẹ lati sọ ẹdun ọkan mi jade fun awọn ti nba ilu Ẹde jẹ, eyiti iwa ati le awọn enia kuro nile.

Ojojumọ ni awọn dana-dana ti awọn ndana ati alọnilọwọgba kakiri ilu Ẹdẹ ati agbegbe rẹ, ti nwọn si nbi iya jẹ tọmọde tagba

Nwọn nle awọn enia jade kuro ni ilu, eyiti a ko gbọ iru rẹ ni ilu Ẹdẹ, mo ni lati dupẹ lọwọ awọn ọlọpa fun wahala ti nwọn nşe

Inu mi yio dun pupọ bi olori ati awọn agba ẹgbẹ to wa nilu Ẹde ba le kesi awọn Ọlọpa lati mu oju to iru awọn enia ti nwọn di ikoko ti awọn nle awọn ẹbi ati ọrẹ kuro larin ilu nitori ọrọ ẹgbẹ oşelu

Olotu mo dupẹ aye ti ẹ gba mi

Emi ni
L. Oye Lawal
Ẹdẹ

### Ilu Apa-Oja Nfẹ Atunşe

Inu mi yio dun bi olotu ba le gba mi laye ranpe ninu iwe nyin lati kesi Ijọba ipinlẹ Ariwa lati ba wa şe itọju awọn oju ọna wa eyiti ko ba oju mu lasiko yi.

Ọpọlọpọ awọn mọto to nlọ soju ọna wọnyi lo ti ba jẹ tabi pe ki awọn mọto miran ri s'oju ọna na nigbati oju ti ba awọn oju ọna na jẹ to fi jepe ko şe rin fun awọn ẹlẹsẹ paapa ki a to sọ fun mọto.

Ninu iranlọwọ ti a tun kesi Ijọba rere ni lati şe fun ni pe ki nwọn kọ ile iwosan si ilu wa nitoripe Ilọrin ti jina pupọ lati ma gbe awọn alaisan lọ ati pe awọn alaisan miran yio ti ku ki wọn to gbe wọn de ibẹ, inu awa enia ilu na yio dun bi Ijọba ipinlẹ na ba le şe iranlọwọ yi fun wa

Emi ni
Yisa Ishọla
EKO

## E Ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ


## Bọ Lọwọ Ọşo Ati Ajẹ

Iwe egbogi Ajẹbidan 25/ mejila £2
Iwe Ilana Ilana Ifa Iyanrin tirẹ ati etutu rẹ pẹlu Iwosan 20/-22/ mejila £2 5/-
Iwe Egbogi Awogba Aru meji 40/-
Turari isẹgun Ajẹ Ọşo ati awọn abanijẹ O wa fun itaja pẹlu alaka la Pangolo 10/5 Paketi 2/- Ki işe ti ẹnu fifọn bi ara ninu awọn ọja yi aabo ti o nipọn ni ile aiye ni yio wa lori rẹ ati awọn ẹbi rẹ.

Fi owo ranşẹ si
J O SHOYINKA
11, Alaba Street
Odunbọrẹ Mushin.



EGBOGI AWỌN ILU FARANSE

## TESSYDRE

Fun Ọmọ—Ọwọ ati Ọmọde gbogbo



Tessydre jẹ ojulowo egbogi hauhaun ti meji irufẹ rẹ kosi kakiri igboro ilu Naijiria fun itọju ọmọ ọwọ ati ọmọde lati le jẹ ki wọn ma hu ẸHIN ẹnu wọn pẹlu irọrun laisi wahala rara tabi aiko le sun yala lọsan fun awọn iya wọn gbogbo Ọgọrun orişirişi egbogi bayi ni wọn npolowo sinu ẹrọ gbohungbohun ati sinu iwe kika lojojumọ şugbọn ko si eyi ta le fi we egbogi Tessydre rara o, Ọlọgbọn di ori ẹja mu pupọ ninu awọn ara ilu Saro ati awọn Agọnyin (GHANA) mọ egbogi yi dajudaju o ni awọn si nlo fun awọn ọmọ ti wọn ba şẹşẹ bi titi fi di nkan bi ọmọ ọdun mẹwa gbako . Kosi wahala tabi iyọnu inu orun ọ̀ ori aiperi ati inu iwọ osi fekun fekun ewo, kokoro ara lapalapa ara gbigbona igbẹ şişan gburu tabi aikolokun ninu ara, sisu Inu kun kun aiorun ati orisirisi awọn amodi tabi sisan ti o ma nyọ awọn ọmọ ọwọ lẹnu nigba Ehin HIHU gbogbo Tessydre a ma mu ki ehin ẹnu ọmọ rẹ legbara gidigidi ati san pẹlu.

Awọn ọmọ ti o nlo egbogi yi ki saba ma sa rẹ rara tiwọn igbati awọn ba ti nlo dede, ti otutu ki si le ri aye ati duro ni igbaiya wọn ti wọn njẹun daradara nwọn sun gbadun pẹlu yio si jẹ ki ori wọn san pẹlu.

NIGERIAN MEDICINE STORE
4 Tinubu Square Lagos

# Egbe Okpara Youths Brigade Yọ Ajagbe

IBADAN:- Ninu irohin kan to de ile iṣẹ lati ọwọ akọwe ẹgbẹ Okpara Youths Brigade ti ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Ọgbẹni Okunlọla Ọliwẹyi ni o ti ṣe alaye pe awọn ẹgbẹ na ti yọ Alaga ẹka ẹgbẹ na ni Ogbomosho Ọgbẹni S. Ọla Ajagbe kuro gẹgẹbi alaga ẹgbẹ na fun ẹka ti Ogbomosho.

Ninu iwe ti awọn ọmọ ẹgbẹ na ni ipinlẹ Iwọ Orun kọ si Ọgbẹni S. Ọla Ajagbe ni nwọn ti ṣe alaye pe: "awọn ọmọ ẹgbẹ na ti yọ kuro gẹgẹbi Alaga ẹgbẹ na ni ilu Ogbomoshọ lori iwa ti o lodi si ofin ẹgbẹ na ti o ma nhu eyiti kọ ba eto ofin ẹgbẹ na lọ"

Awọn ọmọ ẹgbẹ na tun ṣe alaye ninu iwe ti nwọn kọ si Ọgbẹni Ajagbe pe lati ọjọ kerindinlọgbọn oṣu to kọja yi ti nwọn kọ iwe ti nwọn fi da duro gẹgẹbi Alaga ẹgbẹ na ni yio ti kuro lori aye rẹ gẹgẹbi Alaga ẹgbẹ na fun ilu Ogbomọsho ati agbegbe rẹ.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na tun ṣe alaye pe lati ọjọ na lọ ni ko gbọdọtun pe ara rẹ ni gẹgẹbi ọkan ninu awọn Igbimọ ẹgbẹ na ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Awọn ẹgbẹ na tun ṣe alaye ninu iwe ti nwọn kọ si Ọgbẹni S. Ọla Ajagbe ti nwọn fi da a duro gẹgẹbi Alaga ẹgbẹ na ni ilu Ogbomọsho ni nwọn ti ṣe alaye pe awọn Igbimọ to nṣe eto lori eto ofin tabi ki nwọn jẹ nia to ba ṣe ninu ẹgbẹ ni ya lo si ṣe eto na lati da a iduro gẹgẹbi Alaga ẹgbẹ na.

Ni ipari awọn ọmọ ẹgbẹ na si wa ki Alaga ẹgbẹ na tele pẹ awọn si tọrọ fun ni adura pe yio si se orire.

# Elewọn Kan Tun W'ẹwọn Oṣu Mẹrin

SHAGAMU:- Ni ọjọ ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kejidinlọgbọn oṣu yi ni adajọ ile ẹjọ Ijọba Ibilẹ ilu Shagamu ti paṣẹ pe ki ọkunrin ẹlẹwọn kan Sheidu Bello to wa lọgba ẹwọn ba yi tun lọ fi ẹwọn oṣu mẹrin jura sii lori ẹsun ole jija ti ile ẹjọ tun fi kan ọdaran ẹlẹwọn na.

Gẹgẹbi ọrọ ọlọpa to ba ọdaran na ṣẹjọ fun ile ẹjọ na ni o ti ṣe alaye nigbati awọn ẹlẹwọn ẹlẹgbẹ Bello nṣiṣẹ nia aafin Akariebo ti ilu Ijẹbu Rẹmọ ni Shagamu ni ọdaran na ba gba ẹhinkule wọ to yara kanni na aafin na lọ to si lọ ji ṣe le marun ti ti Olori Awo lesi iyawo Ọba Akarigbo ti Ijẹbu Rẹmọ.

Nigbati ọlọpa na ṣe alaye fun ile ẹjọ tan ni adajọ ile ẹjọ na Ọgbẹni J O Okuwo ren bere lọwọ ọdaran na pe o jẹbi tabi ko jẹbi ni o ba ṣe alaye pe on ko jẹbi ẹsun na.

Adajọ ile ẹjọ na ṣe alaye ninu idajọ rẹ pe ẹni to leni ofin kankan si ijọ wọ (ọdaran) ti o jẹ ọdọ ti o yẹ ki o wa ọna iṣẹ ti yio ṣe ni anfani ju ole jija eyiti yio fi ni owo ojiji.

Adajọ ile ẹjọ na tun ṣe alaye pe ohun ti Bello nfẹ ni wipe ki o yara ni owo ni ọjọ kan na eyiti ki iṣe lori wahala ara rẹ ni yio fi ni owo na bikiṣe ọna ti yio gba fi jl owo na tabi ọna jibiti.

Adajọ na tun ṣe alaye pe nigbati Bello (Ẹlẹwọn) ko ile ṣanu ara rẹ o ni ko si oju anu kankan ti on yio ni si iru enia bayi

Ọdaran na si wa lọgba ẹwọn eyiti o ti nse ẹwọn oṣu mẹfa fun ẹsun ole jija ati wipe ninu ẹsun ti nwọn ṣẹṣẹ mi fun yi ni Adajọ ile ẹjọ ijọba ibile na ti paṣẹ pe ki o yara lọ fi ẹwọn oṣu mẹrin lọ jura lati le fi tanran ẹṣẹ ti o ṣẹ

# Oluwa Yio Bere Lọwọ Rẹ

LATI OJU EWE KEJI

gbagbe ọrọ Ọlọrun ti o sọ bayi wipe Aṣiwere wi ọkan bẹ pe, Ọlọrun ko si, won ba ẹ, wọn si nṣe irira ko si ẹni ti nṣe rere Psalm 14 ẹsẹ 1–7 ki ẹ lọ ka iyoku nibẹ.

Ṣugbọn mo fi awọn eleyi we ay were ọlọrọ, aye ko si fun gbogbo rẹ ṣugbọn ti o ba di igba miran ẹo ma gbo o ki ẹ lọ ka ninu Luku 12 13 21 ati Marku 36 ng o ṣe alaye rẹ laipẹ yi

Nitorina enyin enia ẹ lọ ronupiwada ohunti ofa ipo nju si orilẹ aiye niyẹn, eni kẹni ti o ba si tete ronupiwada yio jogun iye ainipẹkun, mo fẹki ẹ mọ wipe Ẹmi li Ọlọrun bi emi ko tile rini ṣugbọn on ri mi o mọ ohun gbogbo o si le ṣe ohun gbogbo

Ẹ jẹki a ṣọra na gidigidi o ki a si ma bọwọ fun Ọlọrun ẹ maṣe jẹki a titori oṣe u kan sọ Ọlọrun dẹgbẹ wa

Ẹ ma si ṣe jẹki a titori wi pe a ko ri Ọlọrun ki ama sọ isọkusọ o iko si ẹnikẹni ti o le ri idi ṣẹ Ọlọrun ẹ lọ ṣọra nyin o lagbara Oluwa tio ba di ọjọ miran ẹ o maa gbọ apa keji ọrọ mi yi.

Titi di igbana ẹ ma mura silẹ eniti o ba fẹ ki o tete ronupiwada ṣugbọn ọjọ nbọ Oluwa wi ti asiko ironupiwada ko ni fun ọmọ eni gẹgẹbi ti Lasaru ati ọlọrọ ọjọ kini.

Eniti o ba ni eti ki o gbọ ohun ti Ẹmi nsọ fun awọn ijọ eniti o ba ṣegun ni Ẹmi o fi eso igi iye ni fun je ti mbe larin Paradise Ọlọrun (Iwe Ifihan 2 ese 7)

O digba die na.


## Iwo Ha Nfẹ Ile L'Eko Bi ?

| | |
|---|---|
| Room | £5 |
| Rom and Parlour | £6 |
| Room and Shop | £15 |
| Shop and Parlour | £12 |
| Room at Idumagbo | £5 |
| Room | £4 10/ |
| Room | £4 |
| Room | £5 |
| Room Parlour | £11 |
| Flat | £18 |
| Flat | £20 |
| Shop | £3 |

Ti o ba nfẹ okan ninu awon ile wonyi yara tete lo ri Ọgbẹni ODUS:— 187, Bamgboṣe Street Lagos.

Ni deede agogo mẹrin irolẹ si agogo mẹfa Irole, ijafara lewu anfani nla kan ni eyi je fun o pe, o ri ile l'Eko

## Kini E Nduro Fun

Bi o ba ni Aṣọ fun fifọ Ati lilọ bi wolen aṣọ oke, Tafẹta Sapẹti ati oriṣiriṣi aṣọ ti o ba ni fun fifọ ati lilọ ni iṣẹju kan.

TETE GBE WA SI ỌDỌ

JOYCE LUNDRY DYING & DRY CLEANING SERVICE

9, Fatiregun St, Brickfield
Apapa Road Ebute Mẹtta

Kia ni ao si fọ ti o ri gba nsẹ lẹkan A le wa gba ni ile rẹ, ki a ko pada fọ bi aba fọ tan kọ nọmba ile rẹ ranse si wa dan wa wo lẹkanṣoṣo ki o si ri bi iṣe wa titi.

Owo pọọku ni a si

